GREAT SALE TILL END OF MONTH.

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. III. No. 154. SATURDAY, JUNE 27, 1925. 4d.

**Declared Circulation 1,700 Copies Weekly.**

Ṣe ara rẹ l'ọṣọ pẹlu ẹwu ati aṣọ ayo to si dinwo pupọ

Startling reductions on Shirts, Singlets, Chemise, Silks, etc.

## White's Golden Female Tonic
**(NATIVE)**

A splendid Remedy for female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhœa (White's), Cramps Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A tendency to Miscarriage etc., etc.

**Price 10s. per Bottle.**

**Made and sold only by** VICTOR WHITE, Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*Packing & Postage 2/6d. extra.*

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO **J. F. SICK**

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirisi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita :—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumădan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aṣọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aṣọ Iş'ọşọ, Ẹrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni:—Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

JOHN HOLT'S FANCY SHOP, Broad Street, Lagos.

# JULY FIRST

**OPENING DATE OF THE**

# Lever Store

AT

# EBUTE METTA.

**Special opening bargains.**

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices :* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | lu miran ni Nigeria. | lu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

O R'ẸSẸ AṢIWERE O BU Ṣ'OGUN ?

Ninu ọwọnlọwọn owo nisinsinyi ni Oyinbo kan Aga-magọ jẹ kumoyo tan l'ọsẹ to kọja ti o bẹrẹ si fọ́n owo ṣile kiri ni Opopo-nla *(Broad Street)* lapa *Office* "Eko Akete" ati lapa Ile-ero *( Hotel )* ti o wa l'eti orori Orimayakiri-a-gbojo-lọwọ-iku ; b'o ba ri bi t'ọmọde t'agba ti nṣikiti bo owo na nigbati o ba da diẹ silẹ gẹgẹbi igbati Adiẹ ndàbo igbado ni ; ti owo tobẹ o ju bẹ̄ lọ, owo a-pe-kanuko.

Nigbati a wa idi Ọgbẹni ti o nṣe bi ọlọba bayi ; a wa ri pe ṣango inu àgbá, ọya inu ṣago ni !

TITI AIYE MI NG KO DE'BADAN MỌ, O !

Irufẹ orin yi ni Awa-mọto kan mu kọ nigbati awọn Alagba mẹfa *( Coroners Jury )* da silẹ ni Kotu Kantanyan l'ọsan *Monday* ọsẹ yi, nigbati awọn Agbagba na ni ko jẹbi ẹsun ti a fi sun pe o wa mọto rẹ *L84* fi kọlu ọkọnrin kan ti o njẹ Mọmọdu ti o ngun "ẹṣin gb'emi d'Ereko" rẹ *( bicycle )* lọ si apa Ita Tinubu ti o lọ se pẹkirẹki mọto na ti iyẹn rún wó-wò-wó, a goe Mọmọdu yi lọ si Ile Alarun o si ku laipẹ nitori irora kikọlu mọto na ; awọn *Jury* ni èṣì ( *accident* ) ni kikọlu na ṣe ; a si da Awa-mọto yi silẹ k'o ma lọ ; bi ọkọnrin yi ti sọkalẹ, bẹ lo ndupẹ lọwọ awọn Alagba ti o ndọbalẹ pe titi aiye on, on ko ni f'ọwọ kan mọto ni wiwa mọ. Ọgbẹni S. A. Johnson ti Ile-òwò Ile Alagbọn *( P.Z. )* ni olori awọn Juri yi l'ọsan *Monday* na.

A ro pe itufẹ ewu ti ọkọnrin yi re kọja yio jẹ ẹkọ fun awọn Awa-mọto ẹgbẹ rẹ miran ti nwọn ki nbikita mọto ni wiwa gburu lairọra larin ilu, awọn miran tilẹ ma nṣẹ̀fẹ̀ pe bi enia ko tete kuro lọna fun wọn, awọn yio fi oluwarẹ ṣe bakaya ( ẹran oniyọ ), nwọn gbagbe pe irẹ-idi rẹ ki tun ṣẹ mọ, nigbati ọwọ ofin ba tẹ wọn. Pẹlẹpẹlẹ o ! Pẹlẹpẹlẹ o ! !

AYỌ ABARA TIN-NTIN.

Ni *Tuesday* ọsẹ yi ni Arẹmọ Ọba King di ọmọ ọdun mọkanlelọgbọn gbako nitoripe ni ọjọ kẹtalelogun oṣu *June* ọdun *1894* ni iya rẹ Mary Ayaba l'ori rẹ sọlẹ ni Afin-Ọba ni'lu Oyinbo. Bi a ti nwi yi Arẹmọ na ṣi wa ni isalẹ ilu wa *( South Africa )* lati igbati o ti lọ larin wa nibi ni oṣu *April* to kọja ni ọdunni. A ba Arẹmọ yọ o, aṣeyi-ṣ'amọdun o !

ABỌ O, A-KEWEJẸ.

Ọgbẹni George I. Phillips Ọga-Akewejẹ *( Scout-master )* li Ile-iwe Giga ( *C.M.S. Grammar School, Lagos* ) nibi, pada bọ wa'le lati Abẹokuta nibiti o gbe ti dakan lọ nilọlọyi. Abọ o, o sunan-sunan ṣ'ana ẹbí ( *family* ) " Burọda."

ẸNI MỌ WURA L'A O TA WURA FUN.

A ba awọn Janma Musulumi yọ fun esi ti nwọn ri gba lati ọdọ Arẹmọ Ọba fun ọrẹ ( *present* ) ti nwọn ta a nijelo nigbati Jagun na wa bẹ wa wò ni *Nigeria* nibi. A tẹ ẹdà ( *copy* ) Esì na l'Ede Gẹsi sapakan iwe nihin.

Ẹ KU AGBA, AGBA KU IYỌNU.

Tẹdun tẹdun la fi gbọ ti iku Eunice Adejọkẹ ọmọ Alufa A. Adeniji Puddicombe to ṣẹlẹ ni Ibadan ni ọsẹ yi, ni Ile-we Giga Obinrin ti ọmọde-binrin na nlọ :

A ba Alufa ati Mrs. Puddicombe daro "ina" apapandodo ti o "jo wọn" yi ki Baba maṣai rẹ nwọn lẹkun.

Ẹ KU EWU.

A ba Ọgbẹni S O. Odutọla ti Ile'we (*C. M. S. Gramm ır School*) nilẹyi, 'yọ si ọmọ titun kan ti Iyawo rẹ Mrs Odutọla fi ta lọrẹ.

---

## WESLEYAN OLOWOGBOWO SUNDAY SCHOOL LAGOS.

On the 2nd of March last 43 scholars from the Weslevan Olowogbowo Sunday Sch ol sat to the London Wesleyan Meth xdist Connexional Scholars' Examination which took place in the Wesleyan Boys' High School Hall.

The results of the Examination are as follows :—

| Division | Sat | Passed 1st Class | Passed 2nd Class |
|---|---|---|---|
| I | 11 | 5 | 5 |
| II | 8 | 5 | 3 |
| III | 13 | 12 | 1 |
| IV | 1 | — | 1 |
| V | 10 | 8 | 2 |

On the whole 7 passed with Honours, 30 obtained 1st Class and 12 2nd Class Certificates.

All the divisions did well, particularly division III which obtained four out of the seven prizes gained by the School.

| Honours List :—Division | | | |
|---|---|---|---|
| | I | Thomas Makanju | 90 |
| „ | II | Titi Pearse | 92 |
| „ | III | Sam Nayon Thomas | 100 |
| „ | „ | J· Ajayi Cole | 94 |
| „ | „ | Olndare Goyea | 90 |
| „ | „ | Esler Thorpe | 90 |
| „ | V | Kanbi Oyebolu | 96 |

The general result of this year's examination is second to none of the result of previous years with the sole exception perhaps of those of the first effort made by the School in 1918 when all the candidates were successful.

It is hoped that the publication of this result will tend to stimulate parents and guardians to show more interest in the efforts of their children in Bible Study, as on this alone depends the laying of solid foundation for their future.

ISAAC O. WILLIAMS,
*Secretary.*

---

## Stop Press News.

This morning at about 10 o'clock, we learn, a certain number of princes headed by Yesufu Ọba, etc., presented Prince Ibikunle Akitoye to the Government as the new Head of the Royal Family at Isalẹ Eko, and that he was accepted.

A Squad of the Colony Police has been detailed for duty at the Palace (Iga Idunganran) since the 25th instant.

—*Eko Akete* wireless.

## DUGBẸ-DUGBẸ L'ORI ILE DOSUMU
### ỌBA-NGIJI KO NI JẸ O JA!

Si Oniwe-Irohin "EKO AKETE."

Iba o!

Ọrọ tamutamu ti *Atari Ajanaku* sọ l'ọsẹ to kọja ati ti Ogbẹni Makọli ninu Iwe Jackisini ti *June* 13 lori dugbẹ-dugbẹ to nfi ṣugbọn ti Ọba-ngiji ko ma jẹ o ja sori Ile Ọba wa nipasẹ iwe-itan, iwe-ọran, iwe-ọtẹ, ti-ko-le-tan ti awọn apakan idile Ọba-n'Iga kọ ranṣẹ si Eleko Ọba wa ti nwọn si kan si Ijọba (Gẹsi) pe ki Eleko fi Iga silẹ ki awọn ba le yan ẹlomiran sile ki iregbe ati asọ ojojumọ ati idunrun wa le tan nilu. Inu ẹnikẹni lo ni lati dun pe *Atari Ajanaku* kesi t'ẹru-tomọ, t'onile-talejo, ati Oyinbo ati Dudu, ati Adele-Gomina ati Birrel-Gray ti nṣe Balẹ Ilu, pe ki gbogbo wa gba majẹ ki gudugbẹ na bẹ sile. A ni ero pe gbogbo Oloye ati Ọmọ-Ọba, ati Ọmọ Oloye, ni yio si ṣe akiyesi ipe ti aṣiwaju wa pe gbogbo Oyinbo pọ mọ 'wa fun idile Oba ati ipo Ọba wa, Eleko.

Ko dede Nwọn ni "Bi yio san agba, bi yio san agba ni agbalagba ki ṣe p'okete bọri." To to o! Iwe Oniwe-Irohin wa yi ti ọsẹ to kọja ni idahun si Iwe Jackisin to fi fẹ ba *Eko Akete* ati *Eleti Ọfẹ* jẹ larin ilu lọ de ẹhin-odi pe Ọdalẹ ati Alabosi ni wọn, lori irufẹ ọrọ bayi na ni o ti ṣẹ. Nigbati Gomina Agba mbọ wa fi ilẹ-yi silẹ patapata, gbogbo ara-ilu to ba fẹ ire-ilu to si duro ti ilu pẹlu ọkan kan ati inu kan lo ni ifẹ pe ki Ilu parapọ ṣeto ati ẹyẹ ki inu Ijọba le rọ si ọrọ Ọba wa ti a ti pa kalẹ. Ka tilẹ ni ko le yanju patapata lẹsẹkanna, ṣe "ariṣe l'arika" gẹgẹ bi owe awọn Baba wa ṣugbọn ọna ti awọn atọkun-ilu gba ko ya gbogbo ọmọ-de ilu l'ẹnu pe "aiye re!"

Ki l'a tun ri, ẹwẹ? Awọn Oloye ti Oluwa si fi ṣe olola, ti a si naga pe nwọn yio mu ọran Ọba yanju, awọn na ko si tun ri agbako pẹlu Ijọba? Nigbati a si nke pe, ewọ, ki a ma gbọ o. Ẹ ma jẹ ki kiniyi dabi t'ana. Ki l'a tun ri. Ṣe awọn atọkun-ilu ti a farati na lo si tun fọn kun jomu pe, ẹbẹ abi kin'la! Awọn Oloye gbaṣẹ ni ti nwon ma fi lọ s n Clifford, abi nwọn ngbowo oṣu, abi ore kini Cl fford ṣe fun wọn? Aun nla lo si ṣe opọlọpọ ẹniti ọran ilu ko nṣe nkan ariya, ere, ẹfẹ, tabi ewo-lo-gun wọn mbẹ, lati ri pe *Atari Ajanaku* papa si kinrin nwọn lẹhin pe awọn Oloye ko ṣe nkankan. Nigbati awọn Iwe-irohin miran ko sọrọ odi si Ilu, ti nwọn ko bu awọn Oloye, ti nwọn ko si ni ki nwọn fi'ra wọn ṣẹru Oyinbo, ṣe bibu ni nwọn nbu wọn nitori pe nwọn wo iwaju, nwọn si ri pe fun ire Eko—nitori ẹhin-ọla—ki awọn Oloye fọwọ wọnu ki nwọn tọrọ aforiji Ijọba —ti Birrel Gray kọ o, nitori ẹla lọrọ—ki nwọn ba wa firi-de-firi (*free*) lati ba Ijọba ṣe pọ k'ọwọ wọn lẹ to ohun ti a ndaniyan.

"B'ọmọde ba ngegi, agbalagba a ma wo 'bi ti yio ṣubu si," Owe ẹnyin agbalagba. O dabi ẹnipe ọmọde lo si wa nfi lakaye gbe ọrọ ilu nisisiyi.

Nigbati a tun ma gbọ, ti ebu awọn Oloye ni a tun gbọ. Sibẹ na oporo iwe ti ilu, *Advocate* ati *Eleti-Ọfẹ* nipataki, fihan Ijọba pe iwọsi ni ti ọrọ na ba jẹ otitọ, nwọn si ni, sibẹ na, ki awọn Oloye fi suru gbe, ki nwọn fi ọgbọn yan a. Ebu ni a tun ri pe awọn ọmọ-oni-lakaye to fẹ ire wa ati iduro awọn Oloye wa tun gba imọran yi. A nṣubu ṣere ambọtori k'a dọbalẹ ki ana ẹni. Nwọn ni ohun ti a ba nwa ni igbọn ju ni lọ. Nisẹnyi ti a wa ri pe o tọ k'a kesi Balẹ Ilu papa, ko wa han pe ọrọ wa fẹ ẹdẹ, suru on lakaye? Ariwo ku: "Kini-nla! Bi Ijọba da wọn duro iyẹn ko rọwọn l'oye," ati gbogbo marari-mara tọmbọrọ ti a ti ngbe l'ankẹ rẹ ko wa han pe yẹyẹ ni? Bi awọn ẹni wa ba bọ ṣokoto ti nwọn lọ ba Balẹ Ilu. ọrọ ko ti ni yanju, nipo ti a fi ntubọ gun awọn Oloye ni kẹṣẹ ninu, ti a si nfọ lùru da mọ ṣapa?

Ọrọ re, ara Eko! Ọpa wahala to gbe ti ki ọrọ le ṣe kan. Ẹ jẹ ki a bẹ awọn Oloye ki nwọn ma binu ojọ. Ki nwọn ma gbagbe pe lati ọdun kẹrin abọ ti Ọba ti di ẹni-aṣati ti Ijọba pẹlu aiṣati nwa, ko le ṣe bi Ọba. Gbogbo awọn Oloye tuntun ni ko le de Fila-Oye. Ẹyọ ko le jade. Ọba ko le la sasabo s'ode. Bẹni Ilu nfẹ ẹ. Ẹ o ri akan. Ki Mọmọ ti mọ eyi tan k'o wa ni k'awọn Oloye ma bere bi nwọn da wọn duro bi nwọn ko da won duro.

Nwọn nkọ wa pe ki a pe ọkọ-l'ọkọ. Iyẹn dun. Ṣugbọn Yoruba a ma sọ pe "gbogbo aṣọ kọ la nsa lorun," abi otitọ kọ l'a ma nfi ẹjẹ sinu tutọ funfun s'ode. Abọ ọrọ la nsọ f'ọmọluwabi o!

A pa gbogbo alọ oke wọnyi ki o ma di ti Elenpe iṣaju ti asọrọ-ailadi pa. Ki Ilu f'orijin wa o. K'Ọlọrun, jẹ ki a le ma sotọ inu o. Awọn Oloye yio fi Oye l'ọmọ wọn lọwọ o! Olokun, Ọlọsa yio gbe ipo Eleko ro, *Amin*! Aṣẹ! Imọran wa ni pe, k ẹniti ọkan rẹ ba wa fun ilu nitotọ ko fi yedenu se ọrọ ilu ni oran ẹdun, ki o si ṣe iranlọwọ lati mu irẹpọ ati alafia wa si arin gbogbo wa. Ki ebu ati ọrọ iṣọnu ṣi wabi joko si na. Irẹpọ awọn Oloye pẹlu Ijọba koko nla ni. Nitorina ewu, ewu, ewu nla ni ipo ti nwọn wa nisisiyi. A kesi Makọli, Jackisinni, ati awọn alabaṣe wọn ki nwọn fi han awọn Ojoye Eko pe ija ko yẹ wọn pẹlu Ijọba ni sa ti a wa yi. Ere ọmode ni ti awọn Ọmọ-Ọba to nda inu ṣe bi awọn Oloye, Ọmọ-Ọba ati Ilu ba rẹ ti nwọn si gbede ara wọn. A gbọ pe Ojọra ati Oniru ti ṣajo ati yanju tiwọn. A ni tanma pe bẹ ni awọn Oloye yoku yio ṣe pẹlu. B'awọn ba wa, ti nwọn duro ti Ijoba, ti nwọn nsa ipa lati ba Ijọba ṣelu, l'agbaro Soko, ọna yio la fun ti Eleko. Otọ wu wa ju itanjẹ lọ. Awa na le-ke pe: Wọnyin! Ma da yẹyẹ lohun. Nibo ni Birrel Gray ti wa. Tani bi! ṣe o wa ni, lilọ ni yio gbẹhin rẹ. Ẹrin pa wa titi t'a ba nri fina-fina ti awọn elomiran nyan l'ode, ṣugbọn ti nwọn nrerin labẹ ehin! Ẹnyin Oloye, ẹnyin Ilu, ẹ fi oju agba wo ọrọ wa, k'ẹ si fi lakaye gbe e, nitori bi a ba ni mọ ọ, ọmọran a mọ o!

T'ojo kọ Ogun ti a ba nja lai bi sẹhin rara ti a ko si wo ẹhin, o le fi ọkonrin han, ṣugbọn o le tun run ogun na tutu tabi ki o sọ gbogbo ọmọ ogun to ba ye d'ẹru. Ko dede. B bi sẹhin agbọ t'ojo kọ rara. Bi ogun ba nlọ, Ọgagun a ma ṣakiyesi ipo ọta bi ogun tirẹ papa ti nlọ, nitori o le ma le ọta lọ k'o rope ogun ngbe on, ki o wa dẹhin ki o ba ra'rẹ larin ọta rẹ lọtun, losi, n'iwa, l'ẹhin, Nigbana ajaku akata, tabi igbekun ni yio kanhin. Bi a ba nba enia lo, iwa rẹ ni a nṣọ ti a si fi nba a huwa. Bi o ba jẹ alagbara a o fi ẹdẹ, ẹlẹ, ati lakaye ma pa a. Ẹsọ, ẹsọ, ni a fi nba a lo. Giri-mọkai pẹlu ẹni to lagbara ju ni lọ, iya lori iya ni. Ti Ọbọ kọ l'a wi o. Oloye l'ọrọ nbawi. Iba ọ! Iyoku d'ọsẹ to mbọ, b'Oluwa ba fẹ.

KEKERE ILU.

---

Abeokuta,

The Editor EKO AKETE,
22 & 24 Williams Street,
Lagos, Nigeria.

Dear Sir,

I shall be thankful if you will kindly permit me some space in your valuable journal to state the following facts regarding Major Birrel-Gray, the Resident of the Colony, father, (Baba) as he was generally called when he was stationed here as Acting Resident of the Province, through his generosity and kindness towards Egba people. I have read with much interest your issue *Eko Akete* of the 6th instant, your letter to the Resident Major Birrel-Gray, and his reply invited you personally to his office when interview began between you and the Resident regarding the meeting he had with the Lagos White Cap Chiefs on Friday the 23rd of May 1925, about their non-appearance in seeing the Governor off on the 8th May 1925. During this meeting Major Birrel-Gray, Resident of the Colony according to the publication of the *Weekly Record* of May 18-23 ultimo used many insulting and abusive terms to all the Lagos White Cap Chiefs, excepting one who has obeyed the Government order by bidding his last farewell to Sir Hugh Clifford on the occasion of his final departure from Nigeria shore on the 8th of May 1925. As an Editor, you have acted very well indeed for the way you arrange your interview with the Resident of the Colony, on the 2nd instant.

According to each question put before him by you and his reply to each question moved me to undertake the task of writing you to-day about this good Resident and to tell you very little of what I know about him when he was here with us as Acting Resident of the Province.

Major Birrel-Gray now a Resident of the Colony of Lagos, is a man of good conduct, quiet, patient, kind and sympathetic to many people when he was staying in our midst here (Abeokuta) in so much that majority of people in Abeokuta gave him the name of Father (Baba) according to his kindness towards the people of Abeokuta. Among

the Resident we have been having at Abeokuta since the advent of the British Protection in Abeokuta. Major Birrel-Gray has taken the lead. If you have any grievance and went to him he will assist the party either him or her, to the last point, he seeks the interest of all in town. If you are without any job and you went to him he is ready to give you a helping hand at once. His removal from Abeokuta has caused many regrets among the majority of people in the town of Abeokuta and large number of people strongly felt his departure from the town. Several petitions were sent to the Governor by the Alake and Council that he may kindly allow Major Birrel-Gray to remain with us at Abeokuta, but the letter or petition did not meet with success to the Egba Administration.

Regarding your question No. 7 to the Resident in your issue of the 6th instant about his past employment at Ilorin which was published by the *Weekly Record* of 18-23 that when he, Major Birrel-Gray was working at Ilorin the natives of that place used to call him Ata.

In the year 1912 when I was under the Nigerian Railways at Ilorin, one Mr. E. C. Duff was then the Resident of the Province, and every native at Ilorin called him Ata up till the time, I left the place on transfer further up the North. Thanking you, Mr. Editor for space allowed.

I am,
Yours faithfully,
OLUMỌ.

---


## White's Golden Male Tonic

*(NATIVE)*

(DOUBLE-STRENGTH)

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. *White's Golden Male Tonic* (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs

**Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,**
*The Reliable Dispensary, 41 Offin Road, Lagos.*
Packing & Postage 2/6. extra.
**SHAKE THE BOTTLE.**

### AREMỌ FUN ỌKỌNRIN

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nje pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo Arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

N.B.—O yẹ ki gbogbo ọkọnrin ma lo igo mejimeji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price ten shillings (10/- per bottle).


Marine Headquarters,
Lagos, Nigeria,
19th June, 1915.

Dear Sir,

I shall be glad if you will be good enough to publish the undernoted news in your valuable journal for the information of the general public:—

"Mr. E. S. Boardman, Office Superintendent of the Marine Department celebrated his 50th Anniversary on the 18th instant in his residence at Igbosere Road when a Special Service was conducted by Rev. A. F. Cole, Circuit Superintendent, Tinubu Church, assisted by Patriarch J. V. Pratt: followed up by an address delivered by Mr. D. G. Williams of the same Department, when presentations of one Holy Bible and a Watch were made to him by the Marine African Staff. Refreshments were liberally served thereafter."

Yours respectfully,
S. JAMES MARSH.

---


## Saccharine! Saccharine!! Saccharine!!!

*Purer than Sugar, Sweeter than Sugar, Cheaper than Sugar and more economical than Sugar.*

Try it in your Cup of Tea Coaca, Coffee or in your Oats or Paps, you run no risk.

Saccharine is absolutely harmless even to the most delicate system; it is very good for young and old, it is now in use in many homes "A boon to those who do not take Sugar and to travellers." If you are in doubt consult your physician.

1 Bottle of 600 Tablets for 1/3d.
1 " " 500 " " 1/-
*Good Bargains.*

Apply to the Manager :—
APALARA STORE,
72, Great Bridge Street
Enu-ọwa.

P.O. Box 772,
Lagos, Nigeria.


---


## TO LET OR LEASE.

All that piece or parcel of land with the buildings thereon situate at 106, Denton Street, Oyingbo Market, Ebute Mẹta.

Apply to the EDITOR.


---


**Mrs. Beckley of No. 53 Broad Street, begs to announce that she has started cake-baking of all kinds; ever ready to serve!**

Government House
Nigeria
8th June, 1925.

No. 82/1925.

Sir,

His Excellency has been desired by His Royal Highness the Prince of Wales to convey to you His Royal Highness's sincere thanks for the beautiful ivory carved Staff which His Royal Highness has been pleased to accept as a souvenir of his first visit to Lagos.

I am,
Yours faithfully,
*( Sgd )* H. DE B. BEWLEY.
*Private Secretary*
*to the Officer Administering the Government.*

Chief Imam
of the Jamat Muslims,
Lagos.

## Sailing Intelligence.

(Bi Awọn Ọkọ Elefin ti ma şi kuro ni Liverpool ati ni Eko niyi ).

| | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| *Elmina* leaves | Liverpool | 8th July | Leaves | Lagos | 31st July |
| *Aba* | „ | „ | 22nd „ | „ | „ | 14th August |
| *Adda* | „ | „ | 5th August | „ | „ | 28th „ |
| *Abinsi* | „ | „ | 19th „ | „ | „ | 11th September |
| *Appam* | „ | „ | 2nd September | „ | „ | 25th „ |
| *Aba* | „ | „ | 16th „ | „ | „ | 9th October |
| *Adda* | „ | „ | 30th „ | „ | „ | 23rd „ |


## Electric Novelties.

MARVELLOUS BARGAINS.

Mr. M. Sadiku has assorted kinds of Electric Materials, 2 & 3 lights, Brackets, Shades, etc., too numerous to mention.

And also undertakes the contract of wiring houses at very reasonable prices.

He has also in stock louder bells complete with wire and Salamonical ready for connections. Please call at 18 Ọbun Eko Street, Lagos and make your selection.

*P.O. Box 378.*


### A O KO ỌLAYIWỌLE JADE NI-IJỌ MẸJỌ-ONI.

Adam Alafin Ọmọde-Mẹşẹ yio ko ọmọ rẹ Hizibatu-Lahi Ọlayiwọle Agbekẹ Akọnkẹ ti Iya-afin Nimọta Aşabi bi fun ni *( 6th of May 1925 )* jade ni ijọ mẹjọ-oni *( 4th of July )* ni ile rẹ No. 4 Bajulu Street, Isalẹ-Eko.

Ọrẹ, lọ wo Ẹgbẹ Ọmọde-Mẹşọ ni ijọ na lati jẹri bi Mẹşọ ti o gbamuşe ni nwọn tabi Mẹşọ-Ogbẹri.

Otitọ ni o bori Eke


The West African Soap Co. Limited
APAPA, NIGERIA

*Manufacturers of*

NEPTUNE
PALE SOAP

BUGLE
PALE SOAP

MAGNET
CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

P.O. Box 522
Lagos
Nigeria

P 393

EKO AKETE

EKO, SATURDAY, JUNE 27, 1925.

## ỌBẸ̀ L'ỌMU AGBÀ.

Kekere kọ ni iṣẹ ti ọbẹ̀ nṣe lara awa ọmọ Anọbi Adamọ, pāpā ti ọbẹ̀ na ba "jé" ti o si fanimọra; a sā ri odidi ọkọnrin ti o ṣigbò tọ obinrin miran lọ nigbati ẹlẹgba-ọmọ-asẹhin na ti mọ "Kọtọ" ọbẹ̀ didi tan; awọn ẹlomiran si sọ pe awọn "ẹlẹgiri" miran wa ninu awọn "Iya wa" wọnyi ti nwọn mọ jẹ ki ọbẹ̀ ma sọ "Tapa" lori ina, tobẹ ti nwọn yio fi gb'ọkọ lọwọ ọlọkọ, bi oyì mimọ-ọbẹ̀-sise ni asegbadun ko ba ti dá loju irufẹ aya bẹ̃; ẹ̀wẹ̀, bi ọkọnrin miran ṣeṣi ri atọhunrinwa-obinrin kan ti yio ma "p'ata si l'ẹnu" nipa didin ọṣinṣin fun u, ti o ba si jẹ ọkundun enia nipa gbigbadun ọbẹ̀ bẹ̃; bi-ere-bi-ẹwa ni ọkọ yi yio ṣa aya rẹ ti ile tì, bi igbati iṣa iba ṣa ọkọ-wete tì l'ọsa, ọkọnrin na ibā fun aya rẹ l'oruka Arede—*stubborn pan* bi aṣa awọn Saro—mẹdọgbọn: nitori ọkọ na yio ri ro pe pademi-nigbọnwọ-ọbẹ̀ ti obinrin on nse fun on lo mu sababi bẹ̃ wa: a ha le da irufẹ ọkọ bẹ̃ l'ẹbi kan gunmọ bi? Kodaju; ohun ti o si mu ni sọ bayi ni pe ṣaṣa ọkọ lo ẹ ki a ma gbọ ariwo "nwọn tun de o" nile on, lori ọrọ iṣasun pe"Iyawo mi ko mọ onjẹ sise, nṣe ni okẹlẹ nluwẹ lagbami ọbẹ̀ ti o ba sè;" ọran ọbẹ̀-didun ko ri bẹ̃, ọmọ-iya; ohun ti o mu odidi Lọya kan niiẹ yi ni iwọn ọdun 1916—o jẹ ọdun mẹsan nisisiyi—lati ṣe iwe kan fun tita to sọ ni "Kilo o jẹ loni, Bāle mi"? Kuro ni ṣereṣere: ogo si ni Ọgbẹni kan njẹ oriki yi, ni akoko kan ni'lẹyi, ẹ gbọ oriki na:—

"Ọrọ-ngọdi baba ọbẹ̀,
A-b'ọbẹ̀ ni'pọn lara,
A fai l'obinrin s'Ọrọ-ngọndi."

Eyiyi tun mu wa ranti pe awa Yoruba ki i ko iyan adidun-ọbẹ̀ kere; nitori idi eyi ni a se npa a lowe pe:—

A nki i, a nsā, o lọ m'ẹni to kú; a ni "O lọ o, oniṣasun ẹran"! O nbere bi ọkọnrin lo ku ni tabi obinrin, ọkọnrin a ma ni iṣasun ẹran? (Ṣugbọn nwọn ma nni l'aiye idayi o). Ki awọn ọmọge le jafafa ninu onjẹ-sise lo nmu ki awọn obi ati awọn alagbatọ ọmọ, papa ọmọbinrin ma ṣ ofin-toto lati kọ ọmọ bẹ ni gbogbo iṣẹ-ile ṣiṣe, iba ṣe onjẹ sise ni, nigbati nwọn ba ṣi wa ni *Lady*.

Eṣu ṣe irufẹ obinrin bayi pe lẹhin igbati a ba ti gbē niyawo tan, ki o maṣe mọ ipò ọ̀rúnlá yatọ si ipo epo, tabi ipo ẹgunsi yatọ si ipo iṣapa-toro-mọ-yan; bi o ṣeṣi gbagbe ọkan ninu awọn irojá wọnyi nigbati o ba ni on nse'bẹ ti o si se "olomi-ṣoroki" fun gbogbo ile jẹ, iyawo na ko ni ti i kuro ni *kitchen* ti yio fẹrẹ ma gbọ ọkan-ko-jọkan orin Gunbe bayi, ti awọn ara ile na le fẹrẹ lọ pe M.M. pe ki o mā jẹ ki Gumbe sọ t'ẹnu rẹ; b'o ba ngbọ "Gba-ngba-rigidi rigidi, rigidi, gbagba-ngba ti-ko-tiko tiko" M.M. lo nfẹsẹ dara lori ilù ũn! Ngbọ, Ajigbeda, õ y'o f'ẹsẹ rā diẹ bi? Nit'oni fẹrẹ? Hẹn, o di ṣiṣe nũn!!!

Iyawo mi da'lasa mọ'yọ,
Iyawo mi o!
Iyawo mi f'ewuro j'ọbẹ̀,
Iyawo mi o!
Iyawo mi s'ela kò l'adun,
Iyawo mi o!

Lati maṣe jẹ ki ese-koyi-ana wà, ni o fi ndi ọran-iyan fun ọmọge-kọ-'mọge tabi awọn iya-afin lati "yege" mimọ "Kọtọ" sisè. Ṣugbọn obìrí aiye ti yi pada nisisiyi, Oniṣango ti d'Ọlọya: awọn Awẹro, Sabina ati Ṣi'au ti di ọlọbẹ-siseta; tẹ'ti le'lẹ na, Gbemisọla ti ebi ti pawọra bọ lati ibi-iṣẹ: "Irẹsi mi jojo"! bayi li o ma gbọ kakiri Eko nisisiyi, papa ni ọja Ereko tabi Ita Faji lẹnu awọn iya-afin wa wọnyi ti nwọn nse onjẹ ta; sise-ọbẹ̀ ta lọna yi ko lẽwọ, ṣugbọn kini ọbẹ na ti ri o, arakọnrin? Ni koipẹ yi ni a ri irufẹ ẹran-mọṣaṣi kan ti awọn miran ninu awọn obinrin nse mọ ọbẹ̀ ti nwọn nta; bi o ri ẹran na, ara a ri ẹ, jàti-jàtì ifun-ẹran ti o ti bajẹ ati awọn jọ̀lọ-jọ̀lọ̀ ẹran miran ti o ti so kobikobi arun, ni ọgọrọ awọn obinrin-alaseta wọnyi nta fun awọn ọmọ-ṣukuru ati fun awọn ẹlomiran ni igboro wa; a ko sọ pe gbogbo awọn obinrin-alase "Ọlọbẹ-danu" wọnyi ni nwọn nhu irufẹ'iwa yi, awọn miran tilẹ

wa ti nwọn nṣe afinju si tiwọn tobẹ ti o ẹrẹ le la awo ti nwọn ba fi bu onjẹ fun ẹ ni alafọ nitori bi ọbẹ nwọn ti dun to, ti ẹran wọn si da ṣakaṣaka: ṣugbọn awọn "Anti-Akona" ti nwọn ni lọwọ ti nwọn si di s'ẹsẹ nipa sise jalajala ati ẹran ti o ti bajẹ ti o si nrun fun awọn enia nkọ? Nwọn ki yio ṣiwọ iwa "ina" yi? Bawo ni ẹnikan ninu awọn obinrin wọnyi ti le ta onjẹ fun ẹniti a nawọ owo ọba-kurumọ tabi owo ṣile ti o ni "Mọmi a-kori" ninu fun u, tabi ki ẹnikan nawọ owo Faranse tabi eyiti ọba rẹ ti yọ bi ori si irufẹ obinrin alaseta na, o jẹ gba a? Arara! ti nwọn ba nsaba kọ irufẹ owo ti nwọn mọ pe ko dara bẹ, bawo ni nwọn ti ṣe nta ẹran-aidara, ẹran rirun fun awọn enia o? A bere! irufẹ awọn obinrin onitakuta bayi ko mọ pe "mimọmọ se ẹran bibajẹ tabi rirun, ta fun enia le sọ irufẹ obinrin bẹ di ero-ẹwọn fun Ṣupa mejila!!!" Ẹ gbọ bi Ofin *Nigeria* ti wi, ani Ofin Amunimuye ti o mbẹ ninu iwe na—ẹ ba ni ka a. *Laws of Nigeria, Vol. 1, Chap: XXIII Page 230: Sec.* 243:—

**"Any person who sells as food or drink, or has in his possession with intent to sell it as food or drink, any article which has been rendered or has become noxious, or is in a state unfit for food or drink knowing or having reason to believe that the same is noxious as food or drink, or is in a state unfit for food or drink is guilty of a misdemenour and is liable to imprisonment for one year"**

Itumọ rẹ ṣoki niyi ni ede wa:—

Ẹnikẹni ti o ba ta onjẹ tabi ohun mimu, tabi ti o ni wọn ni ikawọ rẹ lati ta ṣugbọn ti onjẹ tabi ohun-mimu na ba ti dibajẹ tabi ki a mọmọ ma se onjẹ bẹ tà nigbati o mọ pe nwọn ti bajẹ ti ẹnikẹni ba si ta irufẹ onjẹ tabi ohun-mimu bẹ, oluwarẹ na yio di "Iyawo" Ọba fun ọdun kan.

Nitorina ni a ṣe fẹ fi eyi ṣe kilọkilọ fun awọn ti o ba ni irufẹ iwa ti a ti nwi bọ bayi lọwọ, nipa sise-onjẹ tà, ki nwọn bã mọ lati sa fun "pakute" yi ninu onjẹ-sisetà wọn. Awa papa la npowe pe "Ma j'ọkun, ma j'ekolo, aiye lo ti mba ni lọ," eyini ni pe enia kò le fi oju rẹ silẹ ki o ma jẹ ẹgbin.

Ohun to ba ṣe abuku, ka ma ṣe s'ọmọ-nikeji ẹni!

## Ẹ Ṣ'ASALATU F'ONIṢẸ NLA

*Salalâhu Alaihi Wasalam!*

[*Lati ọwọ* ATARI-AJANAKU.]

Si Oni 'wé-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Nigbakugba ati ni oniruru ọna ni Musulumi nṣe asalatu fun Onisẹ-nla; l'aisi ani-ani, Anọbi Muhamodu ṣe iṣẹ nla ni aiye, iṣẹ rẹ to, o si poju eyiti enia le ṣe asalatu fun lọ. Ki Musulumi to gbadura, nwọn ni lati kọkọ ṣe asalatu fun Oniṣẹ-nla, ti nwọn ba si gbadura tan, nwọn ni lati tun ṣe asalatu miran pẹlu, bi Musulumi ba ti ri aye to, bi ọro ẹsin ba si ti gbona l'ọkan rẹ to, bẹni o fi nṣe asalatu yi fun Oniṣẹ-nla, ko si si ofin kan pataki ti o wipe a ko gbọdọ ṣe asalatu ju iye igba kan lọ. Ẹniti o ri aye daradara, ti o si le sẹ ara rẹ le ṣẹ e ni igba ẹgbẹrun ki ilẹ to ṣu, laulafia ni, ko ni laifi.

Oniruru ẹsin ni o wa l'aiye, olukuluku wọn lo si ni onigbagbọ tirẹ tabi ẹniti o nsin wọn. Ẹsin Ọlọrun ti wa ni aiye ṣiwaju ọjọ ibi Anọbi Isa, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti Anọbi Muhamọdu, ṣugbọn ọna ti olukuluku ẹlẹsin fi nsin Ọlọrun ṣiwaju lo yatọ si ara wọn, ti ẹlomiran tọ suna, ti ẹlomiran ko tọ ọ.

Orukọ pupọ ni a le da ni orukọ awọn ẹni nla-nla, ti o ti da oniruru ẹsin silẹ, ẹsin ti ọpọlọpọ ẹda si gbagbọ titi di oni-oloni. Ti a ba ndaruko awọn ẹni bi Gautama Buddha, Conficius ati awọn jakan-jakan miran pẹlu, awọn Omiran *(Giants)* ninu ẹsin, ọpọlọpọ enia ni gbẹgbẹlẹ iwọ-orun Afrika ti o wa nibi le ṣai mo wọn, orukọ ẹsin wọn, ati ọna ti nwọn ngba sin si le jẹ ohun ajeji l'eti won; ṣugbọn ti a ba darukọ Anọbi Isa ati Anọbi Muhamọdu, yio tete ye ọpọlọpọ enia, gẹgẹ bi orukọ Ọramfẹ, Ọbatala, Ṣango ati orukọ Irunmọlẹ miran ti dun yungbayungba leti awọn Keferi.

Ẹni nla ni Anọbi Isa, apẹrẹ iwa ifi-ara-ẹni rubọ ni o fi silẹ l'aiye; titi aiye yio si fi parẹ, orukọ Anọbi Isa ko le parẹ l'aiye, ki yio si parẹ ni ọjọ Igbende Alikiomọ; ṣugbọn ọrọ diẹ nipasẹ Anọbi Muhamodu ati Musulumi ni a fẹ sọ loni, nitori "EKO AKETE" miran ko le jade mọ titi a o fi pa Ileya ni Alamisi ọjọ mẹfa loni, l'gbara Baba.

O di ẹdegbeje ọdun o le marundi-lẹgọta loni ti Amina bi ọmọ kan fun Abudulai (Abdallah) ni ilu Mẹka, orukọ ọmọ na a si ma jẹ Muhamọdu. A fẹrẹ le pe e ni Babarinsa ọmọ, nitoripe ọṣu diẹ lẹhin ti a bi i tan ni Abudulai baba rẹ fo ṣanlẹ, ti o ku, ko si pẹ pupọ lẹhinna ni Amina iya rẹ tun fi ilẹ bora. Ape to pe, ọmọluwabi, ẹlẹyinju ẹgẹ ni Amina, arẹwa obinrin ni nṣe, o gun, o si singbọnlẹ; bi ṣẹda ni irun ori rẹ ri, ko si si ohunkohun ti a fi le wipe obinrin l'ẹwa, ti Ọlọrun fi du u. Amina ni ẹwa, o si ni iwa pẹlu.

Lati kekere ni Muhamọdu ko ti ni baba pẹlu iya, ṣugbọn gẹgẹ bi Malu ti ko ni iru, Ọlọrun nṣe

ẹniti o nle ẹṣinṣin fun u ; ọgbọn ati lakaye rẹ tayọ ti awọn ẹlẹgbẹ rẹ ni ilu Mẹka, o si korira itanjẹ, itọ, aiyederu ati iwa buburu miran gbogbo tobẹ gẹ, ti awọn ẹgbẹ rẹ fi npe e ni "Al Amin" tabi olotọ lati kekere.

Ẹsin ti o gb lẹ ju ni Arabia lakoko yi ni Iborişa, larin iborişa yi ni a si bi Anọbi Muhamọdu si, şugbọn sibẹsibẹ, Ọlọrun ti kadara rẹ pe yio şe gudugudu meje l'aiye.

O nba işẹ rẹ lọ, o nşowo pẹlu awọn ara Mẹka ati Mẹdina, ati jakejado gbogbo ilu Arabia, ko si ibiti okiki rẹ ko kan de ; l'aifa a gun lọ titi, nigbati o di ẹni ogoji ẹdun gbako, ni o ri iran, ti Mọleka Jubrilla yọ si i, ti o si wi fun u pe, Ọlọrun ti yan a ni Woli rẹ lati gbe ogun si Iborişa, ati lati jẹ ki gbogbo enia ti o ti mọ ri tubọ mọ, ati awọn ti ko mọ tẹlẹ ri mọ wipe ko si ọlọrun miran lẹhin Ọlọrun Mimo nikanşoşo.

Bayi, ati lẹhin eyi, ni Anọbi Muhamọdu bẹrẹ işẹ rẹ larin ọrẹ, ẹbi ati iyekan, ki o to di igbati o bẹrẹ si tan imọlẹ ẹsin Ọlọrun ni gbangba kakiri ilu Mẹka ati agbegbe rẹ. O di ẹniti gbogbo ilu nkokiki rẹ, o di ẹniti o nni ọmọ-ẹhin, o di ẹniti o nni ọrẹ kun ọrẹ ati ọta kun ọta ni Mẹka. Nigbati idamu ọta pọju ni Mẹka, ti o si ri i gbangba wipe nwọn fẹ pa on, o sa kuro ni Mẹka, o salọ si Yathreb, ti a npe ni Mẹdina tabi Mẹdinat-al-Nabi, ilu Woli, lẹhin na.

A ko ri i ka nibikibi ri wipe Muhamọdu lọ si Şukuru tabi Ile Keu kan, sibẹsibẹ, o wu Ọlọrun lati da a l'ọla, o wu U lati lo o gẹgẹ bi Ojişẹ, o wu U lati lo o gẹgẹ bi Woli Rẹ, lati gbe ogun si Iborişa, ati lati tubọ fi ipilẹ ẹsin Ọlọrun lelẹ larin awa ọmọ Anọbi Adamọ l'aiye.

Itumọ ẹsin Musulumi Islam ti Anọbi Muhamọdu da silẹ ni wipe, ki a tẹriba fun Ọlọrun, ki a fi gbogbo ọrọ mọ Ọlọrun l'ọkan, ki a si gba wipe, ohunkohun ti o ba şe ni aiye yi, ibaşe rere tabi eyiti awa ẹda ka si buburu, a-mu-wa Ọlọrun ni gbogbo wọn.

Nibiti adun ati ẹwa ẹsin Musulumi wa pataki ni eyi wipe ki a fi gbogbo ọrọ mọ Ọlọrun l'ọkan ; ati jubẹ lo, gẹgẹ bi Musulumi, a ni lati ma gbawẹ, a ni lati ma gbadura, a ni lati ma k'irun lẹmarun lojumọ, a ko gbọdọ mu oti, a ko gbọdọ ta tẹtẹ, a ko gbọdọ jale, a ko gbọdọ gba owo ele, a ko gbọdọ şe şina tabi agbere, a ko gbọdọ korira tabi ki a şe keta ọmọ ẹnikeji wa, a ko si gbọdọ huwa aişedede miran gbogbo.

Loni, ọkẹ aimọye enia lo ntẹle Anọbi Muhamọdu lẹhin, gẹgẹ bi ọkẹ aimọye enia bakanna ti jẹ onigbagbọ gẹgẹ bi ilana Anọbi Isa, Jesu Kristi.

Nitorina, gbogbo wa, ati Kiriyo ati Imale lo yẹ ki a jọ jumọ tẹle ilana ati ẹsin Anọbi Isa ; gbogbo wa ẹwẹ, lo si yẹ ki a tun jọ jumọ şe asalatu fun Ọnişẹ-nla—*Salalâhu Alaiki Wasaam !*

Ẹlomiran le wipe, ipa, girimọkayi, pẹlu ida ọloju meji ni Anọbi Muhamọdu fi nmu enia şe Musulumi ni akoko bẹrẹ. K'a tilẹ wipe bẹni *lati* iwọn ẹgbẹfa ọdun tabi jubẹ lọ ti o ti ku nkọ ? Şe oku rẹ lo ji dide lati Sare, ti o nfi ida oloju meji sọ Keferi Eko di Musulumi ? Ẹlomiran le wipe ẹsin gbẹfẹ ni ẹsin Imale, nwọn si ni anfani lati so yigi mẹrin ni o jẹ ki Imale pọ pupọ larin wa. Awẹ ti Imale ngba, irun nigba marun-marun ti nwọn ni lati ma ki lojojumọ, Mọşalaşi ti nwọn ni lati ma para nigbagbogbo ati oniruru nkan miran ti Şẹria ni ki nwọn şe l'ọna ẹsin, idaji eyiti Kiriyo ko nşe, ko le jẹ ki awa gbagbọ wipe ẹsin gbẹfẹ ni Imale. Ati nipasẹ ti Yigi mẹrin, awa ri pe ẹniti o ni obinrin meji tabi mẹta tabi mẹrin ti o nwi yi, ni gbangba, ti o si lagbara lati tẹ wọn lọrun ni oniruru ọna gbogbo, san pupọpupọ, o san ni ọna ẹgbẹrun ju ẹniti o gbe obinrin kanşoşo ni iyawo ti o si bura niwaju Ọlọrun ati enia wipe on nikanşoşo ni on yio joko ti lọrun titi ọjọ iku on ; lẹhinna ti o tun nle 'mu kiri bi Obukọ nikọkọ ati nibaba ti o nyan obinrin olobinrin l'ale, ti o nbimọ ti ko le jẹwọ wipe on ni baba ọmọ na, ti o nba ọmọlọmọ l'ori jẹ kiri, ti o nbere lọwọ aya alaya wipe "Nibo lo ndun ọ, tabi lọhun ?" ani, ẹniti o fẹ obinrin meji si gbangba san pupọ ju ẹniti o fẹ obirin kanşoşo ti okolobinrin miran si ra a mu lọdọ aya rẹ, ti o si nbẹbẹ wipe, "Bo mi, *and the Lord will* bo ẹ !"

Işekuşe ati agabagebe ti o wa larin Kiriyo ko si larin Imale tobẹ ; sibẹsibẹ, awọn Kiriyo a ma purọ tan ara wọn jẹ wipe iwa panşaga pọju larin Imale.

Awọn obinrin onişekuşe tarata ti o wa larin Kiriyo ati Imale, awọn ti a npe ni Alada nla, tani nwọn nfi ada wọn na şa ju, bikoşe awọn Kiriyo apabobo afọnufora ; ti nwọn ko ri owo da ni Şọşi, ti nwọn ko ri owo tọju iya wọn nile, ti nwọn ko ri owo d'aşọ si ọrun ara wọn, ti nwọn ko ri owo tọju alarede ti nwọn gbe sile : loju *Sweety*, loju *Lovy*, loju Ibadi-aran, loju Awelọrun !

Bi enia ba fẹ obinrin kanşoşo, to si joko ti i, o dara pupọ ; nitori wahala kekere kọ ni o wa ninu ikobinrinjọ ; şugbọn Kiriyo melo lo ha njoko ti alarede wọn nikanşoşo nilẹ yi, l' Abẹokuta, ni Ibadan ni Ijẹbu, ati ni ilu Yoruba miran gbogbo? Apẹrẹ wo ni awọn Afa papa tilẹ nfi le 'lẹ ? Ki a ma şẹşẹ sọ ti mẹmba ; Ajopade ha kọ ni Afa miran pẹlu mẹmba njo pade ara wọn lalẹ n'ile obinrin kanna, aya alaya ti Afa ntọwọ bọ iwe fun mẹmba ? Iwa aimọ, iwa amunibuni ni nwọyi, a ko fi Kristi kọ ẹnikẹni bẹ.

Ni alamisi ifâni tabi ọjọ mẹfa oni, ni ọdun Ileya, nitorina ki gbogbo Musulumi jẹ ki a jo jumọ şe Asalatu fun Onişẹ-nla—*Salalâhu Alaiki Wasalam !* Ọdun Ileya jẹ ọdun iranti etutu lati ẹsin pataki ti Anọbi Buraimọ şe fun Ọlorun. Bibeli mimọ ti awọn onigbagbọ *( Holy Bible )* ati Alukurani f ẹnu şọkan pe dipo ọmọ bibi inu Anọbi Buraimọ to fẹ pa lati sin Ọlọrun, ni Ọlọrun pese ẹran agbo ti a pa dipo ọmọ na ; iyatọ to wa ninu awọn iwe mejeji ni pe Bibeli tabi *Bible* sọ pe Isaac ọmọ ti Sarah bi fun Abraham, eyini ni Ishak ọmọ ti Sarta (Saka ọmọ ti Sarta) bi fun Anọbi Buraimọ ni

Buraimọ fẹ lati pa, Alukurani si sọ fun wa pe Ismaila ọmọ Hajrat tabi Sumọla ọmọ ti Ajaratu bi fun u ni; eyini ni Ishmael ọmọ ti Hagar bi fun Abraham.

Nitorina, yála Saka ti kiriyo wi ni o, tabi Sumọla ti Imale wi, *the fact still remians* pe Anọbi Buraimọ fẹ pa ọkan ninu awọn ọmọ rẹ mejeji yi lati sin Ọlọrun, Ọlọrun si fi agbo dipo ọmọ na, apẹrẹ ati iranti eyi ni Musulumi nṣe lọdọdun.

Ki a to tuka ni ibi irun ọdun ni ọjọ mẹfa oni lagbara Allah, lẹhin ti Lemọmu ba ti ke Khutubah tan, ni yio dumbú ẹran tirẹ pẹlu aniyan wipe Nawaitu Sablia ulhiyyatee ala toreei sunatil Mohammadiyat. Bismillahi Allahu akbar Rabbana taqabalminee. Ọlọrun mo ronu lati pa ẹran ileya mi bẹgẹ bi ẹsin Muhamọdu; mo bẹrẹ lati pa ẹran na li orukọ Ọlọrun Ọba ti o tobi julọ. Oluwa gbogbo ẹda, gba a ni ẹsin fun mi.

Lẹhin ti a ba si ti da'ri wa 'le lati Mọṣalasi ọdun, olukuluku Musulumi yio bẹrẹsi dumbú ẹran tirẹ pẹlu aniyan bẹ gẹgẹ. . Hilha tabi pinpin tọrẹ ti awọn Musulumi npin ẹran Ileya wọn tọrẹ tọ suna pupọ; nitoripe a ri i ka ninu Alquran, ninu Suratul-Hardjj Suratu Hâji, áaya kẹrindilogoji pe :—

*Walbudni ja alnaha lakun min shaa irillahi lakun feeha Rhairun faskuroosma llahi alaiha sawafa faith wajabat junoobuha fakuloo minha wa athiemool qania walmuotari kathalika sakharnaha lakun la alakum tashkuroora.* Ki ẹ mọ awọn ẹran Rakunmi ati agbo, a ṣe nwọn ni ami fun nyin lati ma fi sin ẹsin. Ire pupọ wa ninu wọn, fun nyin, ẹ ranti orukọ Ọlọrun lo'ri wọn, a ṣe irun daradara si ara wọn, nigbati ẹ ba pa nwọn tan, *ki ẹ jẹ ninu rẹ, ki ẹ si fun ẹniti o ri jẹ, ati ẹniti ko ni rara;* bẹ si ni a ṣe nwọn ni irọrun fun nyin nitori ki ẹ le ma dupẹ fun mi, ki ẹ ma si ṣe jẹ alaimore si mi.

Imale ko nṣe ẹsin ti enia le fi ọtẹ Ilu sin, gẹgẹ bi awọn Musulumi miran ti nṣe l'Eko nisisiyi; emi ko jẹ kirun lẹhin Lemọmu bayi bayi, emi olowo, emi agbalagba; tani Iwọ na, Iwọ, Iwọ to nta pa, to nfọnga si ẹniti o wu Ọlọrun lati gbe si ipo na pe o ko jẹ kirun lẹhin rẹ. Iwọ, Iwọ ha tobi ju lati tẹle ilana Anọbi Muhamọdu pe ohun-kohnn ko ṣẹhin Ọlọrun, ati pe Amuwa Ọlọrun ni ohun gbogbo laiye ati pe Ligali to jẹ Lemọmu awọn janma nisisiyi, ko ṣẹhin Ọlọrun.

Ki a tilẹ mu ti ẹsin kuro, Kotu Ọba King, Kotu Onidajọ kan, Kotu Onidajọ mẹta gbà pe Ligali olohun iyọ ni a fi jẹ Lemọmu lọna to tọ suna, ; sibẹsibẹ awọn "Koṣeyọ" fi ake kọ'ori; anu si ṣe wa pe o dabi ẹnipe Ijọba papa lo nti nwọn lẹhin lati ta kanrọngbọn si idajọ Kotu ati lati da họuhọu silẹ n'ilu; bikoṣe bẹ, nwọn ki ba ti fun wa laṣẹ lati lọ Kirun Awẹ to kọja ni ilẹ awọn Janma. Ọdun Ileya lo tun nbọ, ṣe Ijọba tun ma fun wọn laye lati tun lọ kirun lọtọ ni ilẹ awọn Janma kọ, tabi Ijọba yio duro ti idajọ Kotu? Eyi ti Ijọba ba fẹ ninu mejeji, nwọn le ṣe; ṣugbọn ti Ijọba ba fi fun awọn apakeji laye lati tun lọ kirun lọtọ l'ọdun yi, bi ija ba de, tabi asọ tabi ariwo, bi ọlọpa ba si mu ẹnikẹni, nigbana ni ao mọ wipe iwa Alagbara lo l'aye *Might is right* ni Ijọba nhu fun wa, ati pe awọn Ijọba kanna to pe Ole wa ja lo tun pe oloko wa ṣọ.

Ju gbogbo rẹ lọ, nigbati a ba nri iwa miran ti ko tọ suna ti Musulumi miran nhu, ti a ba nri obinrin Musulumi to nyan Daddy l'ọrẹ, ti a ba nri awọn alagidi Musulumi diẹ to nfẹ jẹ gaba lori gbogbo Musulumi iyoku n'ilu nitoripe Ijọba wa lẹhin wọn, ti a ba nri Musulumi to nfi ọti Jini gba'wẹ, ti o si nfi Wisiki sọ'nu, ti a ba nri Musulumi ti inu rẹ ndun nigbati awọn panapana ntu omi si Mọṣalaṣi, ti a ba nri Musulumi to nba elegungun mu 'ti, to nba olorișa j'obi, ti a ba nri Musulumi to nta tẹtẹ, Musulumi, to nya wọn ni owo èlé, ani, ti a ba nri Musulumi to nhu iwa bayi, ati iwa miran ti ko tọ suna, ero ti o nwa s'ọkan wa nipe, nibo ni nwọn ma ru u wọ lọjọ idajọ, l'ọjọ agbende alikiamọ.

Nipa adura nikan kọ ni a le fi ṣe Asalatu f'onișẹ nla, bikoṣẹ nipa iwa wa pẹlu; nipa, titẹle gbogbo ilana Onișẹ nla papa, nipa riran ara wa lọwọ, nipa didariji ọta wa, ati lai wa işubu tabi ipalara ọmọ ẹnikeji wa.

Ko și ojulolowo Musulumi kan to jẹ rena Anọbi Isa, Kiriyo ki Kiriyo to ba si ni iyemeji si Anọbi Muhanmọdu ki o tẹ'ti le'lẹ ki o si gbọ ọrọ aladun Thomas Carlyle sọ nipasẹ rẹ ninu iwe ti a npe ni "*Herols and Hero Worship*" o ni :—

"*The word which Mahomet spoke has been the life-guidance now of a hundred and eighty millions of men these twelve hundred years. These hundred and eighty millions were made by God as well as we. A greater number of God's creatures believe in Mahomet's word at this hour than in any other word whatever. Are we to suppose that it was a miserable piece of spiritual legerdemain, this which so many creatures of the Almighty have lived by and died by? I, for my part, cannot form any such supposition. I will believe most things sooner than that. x x x A false man found a religion? Why, a false man cannot build a brick house. If he do not know and follow truly the properties of mortar, burnt clay and what else he morks in, it is no house that he makes, but a rubbish-heap. It will not stand for twelve centuries, to lodge a hundred and eighty millions; it will fall straightaway.*"

A ki tẹlẹ ni a ki gbogbo Musulumi Eko ati ti idalẹ, ẹ ku ọdun, ẹ ku iyedun ki Ọlọrun ṣe e ni abo ọdun fun gbogbo wa. Lẹkan si i, a ke si t'ọkọnrin, t'obinrin, ọmọde, agba, a ke si gbogbo Janma pe ki a jọ jumọ ṣe Asalatu f'Onișẹ nla. *Salalahu Alaihi Wasalamu.*

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

## THE EDITOR'S OBSERVATORY.

### His Royal Highness at 31.

H.R.H. the Prince of Wales attained his 31st birth-day on Tuesday last the 23rd instant: we note, with pleasure, that this particular day met His Royal Highness at Pretoria, where he was engaged in laying a Wreath on the Kruger Memorial, in far-off South Africa.

### An Historic Call.

To our great amusement we casually saw his Lordship The Bishop of Lagos and the veteran prelate, the Right Rev. Bishop Oluwole in the former's side-car L. 279 on their way to Mr. Chancellor Carr's house on Wednesday last at twenty minutes to ten, ante-meridian; a rat-tat on the door brought out the learned chancellor with whom was our African "banker" Mr. E. A. T. A. Johnson; a ripple of laughter followed this casual meeting of THE BIG FOUR. Is n't the meeting historic?

### Push on, Good Old Book!

*Public Opinion* of May 29, 1925, reported the news of the 572 languages into which the Bible has been translated by that incomparable business body—the British and Foreign Bible Society, *Bravo!*

### KABIYESI to His Majesty! Colonel-in-Chief, W.A.F.F.

The following extract of telegram from the Secretary of State to the Officer Administering, which was culled from the *Nigeria Gazette*, (Extraordinary) of the 24th instant, is worthy of general information

"His Majesty has been graciously pleased to accept the position of Colonel-in-Chief of the West African Frontier Force.

This will appear in the *London Gazette* of June 23rd, and will be published on the morning of June 24th.

Please convey to the Force my congratulations on this signal honour."

May be this is the harbinger of the new era into which we British West Africans are now ushered; arising out of the recent visit of H.R.H. the Prince of Wales.

---

[ Copyright ]

## "EKO AKETE" LAW REPORT

[ Lati ọwọ Atolugbokun. ]

*Suit No. 928.*

KISCHINCHAND CHELLARAM
*versus*
FRANK

Claim £7 10 0 and 11/- Costs—Frank ni ki Adajọ jẹ ki on san gbogbo rẹ ni ẹmẹta, *June, July, and August* 1925. Lọya Williams gba. Adajọ si fi aṣẹ si.

TAIWO AJIKE
*versus*
ADUKE ONI

Adukẹ Oni bọ si apoti o ni on fun ni iye owo ti ...ri, o kọ. Taiwo Ajikẹ ni on ko ma fi oju kan ...o, Adukẹ ko pọun kan pẹlu abọ fun Taiwo, o ni on a san iyoku ni ọjọ *Saturday* ijọ kọlẹgun oṣu yi. Adajọ fi aṣẹ si.

ABIBU OKI
*versus*
SADATU AND ABRAM OGUNLEYE

Claim £15. Owo aṣọ ti Sadatu ra ni awin fi Abran Ogunlẹyẹ baba Sadatu duro fun. Sadatu ni on a ma san ogun şile lọsọsẹ. Lọya Doherty ta wa fun Abibu Oki ni ki wọn san pọun marun şile na, Adajọ fi aṣẹ si pe, pọun marun silẹ ni wọn nşeṣa iyoku pọun mejimeji ni oṣoṣu.

*Suit No. 2168/24.*

SIERRA LEONIANS FRIENDLY SOCIETY
*versus*
J. E. SCOTT & OR

The Court ordered £5 ending of June 1925, and the balance ending of July, 1925. Lawyer Harrison appeared for the plaintiff. No Counsel for both defendants. The defendant Scott is sued as surety.

*Suit No. 2929/23.*

BELO MOJOLAGBE
*versus*
ROBERT FAPOUNDA PEDRO.

Claim £14 17 0. Court ordered that £5 paid down and the balance £2 monthly. Lawyer Doherty for the plaintiff.

IN THE SUPREME COURT OF NIGERIA.

Before His Honour Sir R. M. Combe C.J. on Monday the 8th day of June, 1925

MOTION

JOHN KUYE DAWODU—Plaintiff
*versus*
ABIOLA DAWODU—Defendant

Motion filed by the plaintiff to pay the judgment debt by instalment.

Thompson moved on behalf of Hon. J. E. Shyngle. Taylor for the defendant stood and opposed the Motion. After argument by both Counsel the Chief Justice adjourned the Motion for a week in order that plaintiff could be able to raise loan with the premises situate at Apongbon Street, to satisfy the execution Creditor.

Emi ni ti yin nitotọ,
ATOLUGBOKUN

## *J. C. VAUGHAN*

Ti Ile-Oja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Oja *Excelsior* " ni Ita Agarawu, ni oniruru awon ohun ikole fun tita ni owo opoku-oyoku.

O ti nsowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adota odun sehin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni OGBẸNI na jẹ ninu awon onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

OKO tita wa ni owo po o.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "*Gbabiogẹdẹ*" nta Panu-kikole ati kikan-oko, Işo lorişirişi, Kokoro ( Işika ) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalowo, Simẹnti, Oda lorişirişi ati Epo-oda, Fikifiki, Okun ẹro, ati Oşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awon Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abomafo, ni Şobu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, ( l'ebute Olowu ) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, ( l'Anikantamo ) l'Eko.

O nta Iworo ( Golu ) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Oja rẹ fanimora. Ẹ lo ra tiyin nibẹ

### Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at A. Kessler's Establishment, 7, Labinjo Lane, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

### Coffin ! Coffin !! Coffin !!!

With excellent workmanship and finish on sale at Paul I. Samuel's Workshop 40, Campbell Street, Lagos.

PAUL I. SAMUEL,
*Builder & Contractor.*
Residence and Office 72, Igboşere Road
Lagos.

### Ask From Kaduna Stores.

Everything for Bicycles, Motors, and Gramophones. Newly arrived Gramophones and Zonophones, at cheapest prices as follows :—

£1. 10s. od., £1. 15s. od. to £2. 0. 0.

We also stock special Louder Gramophone needles ; these needles play four-records at one time.

Yoruba and English reccords of the latest amusing time.

For Particulars apply to the Manager.

S. A. CLAY
No. 79, Odunfa Street, or
1, Macaulay Street,
Lagos.

**Cable Address :—**
"Steinafrik" HAMBURG

### E. H. STEIN & Co.

**HAMBURG, Neuerwall 16/18.**
**Hildebrandhaus.**
***AFRICAN MERCHANTS.***

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
***P. O. Box No. 505.***

**Agent in Lagos :—**
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

### KERE O!

Iya-afin Mrs. Beckley nşu Akara didun ( *Cake* ) ta nile rẹ, ni 53, Opopo nla, ŏ gbeyawo ni o, rē yan tirẹ nibẹ ; o sami fun omo ni o, rē yan tirẹ nibẹ ; o toro omo ni o, re yan tirẹ nibẹ.

Opoku-oyoku ni owo rẹ.

" O di ọdun marundi-logoji nisinsinyi ti a ti bẹrẹ si ṣe *Mentholatum*, a si mọ ọ kakiri gbogbo aiye bi egbogi ti o wulo fun wiwo:—Otutu oriṣiriṣi, Ọna-ọfun ti o ndun-ni, Ori-fifọ, Arun Awọ-ori, ati gbogbo Arun Awọ-ara."




A HEALING CREAM

**Mentholatum**

Mentholatum has been manufactured for 35 years and is known throughout the world as a medicine of great value for Colds, Sore Throat, Headache, Scalp Troubles and all skin ailments.

*THE MENTHOLATUM COMPANY LTD.,*
*SLOUGH, ENGLAND.*

*Over 16 million jars sold last year.*

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

CATHOLIC.

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

(Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.
ST. MICHAEL'S) Lafiaji.)

MORNING. 7—8 8.30—9.30
EVENING. 5.45—6.30

ANGLICAN

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m. Christ Church, | The Bishop of Lagos |
| 6.30 p.m. do. | The Vicar |
| 9 a.m. St. Paul's (Breadfruit) | The Archdeacon |
| 6.30 p.m. do. | The Curate |
| 9 a.m. St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. do. | do. |
| 9 a.m. & 630 p.m. St. Peter's (Alapako) | Rev. S. V. Latunde |
| 9 a.m. Holy Trinity (Ebute-Ero) | |
| 6.30 p.m. | |
| 9 a.m. St. David's (Jordan) | Rev. J. H. Ogunro |
| 6.30 p.m. do. | |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. D. A. Bababunmi |
| 7 p.m. | do. | Rev. D. A. Tekoe |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | Bro. C. W. Faulkner-Shaw |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | Rev S. A. Pearce |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | do |
| 7 p.m. | do | Bro. E. E. Ajoṣe |

Williams' Memorial Wesleyan Ebute Mẹta)

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a. .m. | | Rev. L. R. Potts-Johnson |
| 7 p.m. | | Bro. J. C. Lewis-Lisk |

AFRICAN

| | |
|---|---|
| 9 a.m. Jehovah Shalom | Bro. J. T. A. White |
| 6.30 p.m. do. | Bro. W. K. Fafunwa |
| 9 a.m. Christ Church (Ebute Mẹta) | Bro. Olaboye Laleye |
| 6 p.m. do. | Bro. T. K. Aderin |
| 9 a.m. Bethel | Rev. Agbayewa |
| 6.30 p.m do. | Rev. J. Ṣotayọ Williams |
| 9 a.m. Zion | " N. J. D. Ṣomuji |
| 6.30 p.m. do. | |
| 9 a.m Salem Church (Ebute Mẹta) | Rev. J. A. Wright |
| 6.30 p.m. do. | Rev. E. David-Ṣodẹinde |
| 9 a.m. Bethlehem Church (Ebute Mẹta) | do. |
| do. | Bro. J. E. Ṣowọnọla |

| | | |
|---|---|---|
| 10. a.m. | African Methodist | Bro. J. K. Coker |
| 7 p.m. | do. | Rev. I. O. Oyekunle |

BAPTIST

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ebenezer | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Ararọmi | |
| 6 p.m. | | |

ISHOLARIAN.

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | The Founder |
| 7 p.m. | do. | Pastor A. Ọkọya |

ST. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Rev. Patriarch J. G. Campbell

AHMADIA (ISLAM.)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe (Central Mosque, Arọlọya Street.)

ZION CONGREGATIONAL

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Kakawa St. | Locum Tenens |
| 7 p.m. | do. | do. |

ARMY

10 a.m. Glover Memorial Hall
Capt. Jones and the cadets.
7 p.m. do.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, J. P. A. Taylor

UNITARIAN

10 a.m. The Minister, (Arapa Hall)
6.30 p.m. do. 21, Williams Street.

AFRICAN FAITHIST KOSMON

5 p.m. 8, Shitta Street. Bro. A. Gbogboade

## IGBẸ L'OWO WÀ.

### EKO.

Bi ọ̀wọ̀ Ekurọ, Epo ati *Cocoa* ti kusi ọsẹ yi leyi :—

EKURỌ

£14 10 0 fun *ton* kan.

EPO.

£26 fun *ton* kan.

COCOA.

£26—£28 fun *ton* kan.

### KANO.

GROUND NUT.

£13 10 fun *ton* kan.

# A. Kessler,

7, Labinjo Lane,

Williams Street,

***P.O. Box 459***

Highly Recommended:

CRYSTALL LAGERBIER
LÖWENBRAUEREI HAMBURG

THE

# Pilsener Beer

*"Crystall" Brand*

*Light & Sparkling*

Per Case

33s.

**Send for a trial case to-day and convince yourself of the first quality of this Beer.**

### GBOGBONIȘE FUN OBINRIN

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ ati orișirịși arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

"SHAKE THE BOTTLE."

A nta Egbogi yi ni Șabu Egbogi Ọgbẹni Victor White, 41, Offin Road, Lagos.

### WO'BI ẸNIKEJI,

Oniruru Posi li o wa fun tita; lọdọ Paul I. Samuel owo wọn bẹrẹ lati Pọun meji abọ titi de Pọun mejila șile mejila. Ẹ le ri wọn ra ni 40, Campbell Street, leti Ile-isin Șọși Ebenezer; ati ni No. 72, Igboșere Road, nitosi *King's College.*

### White's Convulsion-Killer

(*NATIVE*)

(FOR BOTH CHILDREN AND ADULTS)

**Sold only by VICTOR WHITE, Esq.,**
**The Reliable Dispensary,**
**41, Offin Road, Lagos.**

DIRECTIONS:—For adults one Tablespoonful every halfhour until the fit is gone. As a preventive, one Tablespoonful every morning before food. For Children, one desertspoonful, in the same manner.

*Packing & Postage 1½d. extra.*

"SHAKE THE BOTTLE."

### EGBOGI AIPERI.

(Fun Ọmọde ati Agbalagba.)

Akajuwe:—Fun Agbalagba, Șibi ti a fi njẹ iręsi meji-meji ni ababọ Wakati, titi aiperi na yio fi [illegible] oluwa rẹ silẹ. Fun ọmọde șibi kọkan bakanna.

Ki Aiperi ma ba șeni:—Fun Agbalagba, ki a ma fi șibi meji-meji tẹlẹ inu lorọ. Fun ọmọde șibi kọkan. Ki a mi igo na daradara ki a to mu egbogi na.

PRICE FIVE SHILLINGS (5S) PER BOTTLE.

When replying advertisers please mention *"Eko Akete."*

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.